# PAULU GBEJA IṢẸ-IRANṢẸ ATI JIJẸ APỌSTELI RẸ̀

**2 Kọrinti 10:1-18; 11:1-33; 12:1-21**

**ẸKỌ 397 --- FUN AGBA**

**AKỌSORI: “Emi ni inu didùn ninu ailera gbogbo, ninu ẹ̀gan gbogbo, ninu aini gbogbo, ninu inunibini gbogbo, ninu wahalà gbogbo nitori Kristi: nitori nigbati mo ba jẹ alailera, nigbana ni mo di alagbara” (2 Kọrinti 12:10).**

**I Igbeja ti Paulu Ṣe**

1 Paulu fi iru agbara ẹmi ti a fi di i ni ihamọra lati kọjuja si ọta hàn, 2 Kọrinti 10:1-9; Efesu 6:13

2 Awọn alatako Paulu sọ pe iwe rẹ̀ wuwo ṣugbọn ọrọ rẹ̀ ko ni laari, 2 Kọrinti 10:10, 11; Galatia 4:13; 1 Kọrinti 2:3-5

3 Paulu fi wọn sùn fun rirekọja aala wọn ati fifunnu lori iṣẹ awọn ẹlomiran, 2 Kọrinti 10:12-16

4 Ẹni ti Oluwa ba yin ni ẹni itẹwọgba, 2 Kọrinti 10:17, 18; Owe 27:2; Romu 2:29

**II Ijiya Paulu nitori Ihinrere**

1 A fi ipa mú Paulu lati yin ara rẹ̀, 2 Kọrinti 11:1-22; Johannu 8:44

2 Paulu ṣe iṣiro ijiya rẹ̀ nitori Ihinrere, 2 Kọrinti 11:23-33; Deuteronomi 25:3; 1 Kọrinti 9:22; Iṣe Awọn Apọsteli 20:31; 27:41

**III Iṣipaya ti Paulu Rí**

1 A mu Paulu lọ si Paradise, 2 Kọrinti 12:1-6

2 Ki o má ba gbé ara rẹ̀ ga rekọja, nitori ọpọlọpọ iṣipaya wọnyii a fi ẹgun kan si i lara, 2 Kọrinti 12:7-9; Galatia 4:13, 14

3 O n ṣogo ninu ailera wọnyii nitori nigba ti o ba jẹ alailera nigba naa ni o di alagbara, 2 Kọrinti 12:10; 7:4; 13:4; Romu 5:3

4 O gba owo lọwọ awọn ijọ miiran ki oun le waasu Ihinrere lọfẹẹ fun wọn (eyi nì ni awọn ara Kọrinti), 2 Kọrinti 12:11-21; Iṣe Awọn Apọsteli 20:33; 2 Kọrinti 11:8

## ALAYE

**Ajihinrere ti O Tayọ**

Paulu jẹ́ ọmọ ilu Tarsu, ilu ti o gbajumọ fun ẹkọ́. O kọ́ ẹkọ jinlẹ ninu iṣesi ati imọ ijinlẹ awọn Griki. O tun jẹ́ akẹkọọ labẹ Gamaliẹli, Ju, olukọni pataki kan ni akoko naa. O mọ Ofin. Ki i ṣe awọn nnkan wọnyii ni ohun ti n sọ eniyan di Apọsteli ṣugbọn a gbagbọ pe Oluwa lo awọn nnkan wọnyii, O si sọ ọ di ajihinrere ti o pọ̀ ju lọ ti ayé ti i mọ̀.

**Awọn Ohun Amuyẹ fun Jijẹ́ Apọsteli**

Awọn ohun pataki kan wa ti awọn eniyan gba pe eniyan ko le ṣe alai ni ki o to le di Apọsteli. Ọ̀kan ninu awọn nnkan wọnyii ni pe o gbọdọ ti ri Oluwa. Ninu 1 Kọrinti 9:1, 2, Paulu beere awọn ibeere yii: “Apọsteli kọ́ emi iṣe bi? emi kò ha wà li ominira? emi ko ti ri Jesu Kristi Oluwa wa? iṣẹ mi kọ́ ẹnyin iṣe ninu Oluwa? Bi emi ki iṣe Aposteli fun awọn ẹlomiran, ṣugbọn dajudaju Aposteli li emi iṣe fun nyin: nitori èdidi iṣẹ Aposteli mi li ẹnyin iṣe ninu Oluwa.” Ninu 1 Kọrinti 15:8: “Ati nikẹhin gbogbo wọn, o farahàn mi pẹlu, bi ẹni ti a bi ṣiwaju akokò rẹ̀.” Paulu sọ fun wọn gbangba pe oun ti ri Oluwa.

Nnkan koṣeemani miiran ni pe ẹni naa gbọdọ jẹ ẹni ti a pè lati ọdọ Ọlọrun. (Akọsilẹ ipe Paulu wà ninu Galatia 1:11, 12). Nnkan miiran tun ni pe iṣẹ ami ati iṣẹ iyanu ni lati maa tẹle iṣẹ iranṣẹ rẹ̀ (Marku 16:17, 18). Paulu ni gbogbo awọn koṣeemani wọnyii. Oun wi pe: “Nitõtọ a ti ṣe iṣẹ àmi Aposteli larin nyin ninu sũru gbogbo, ninu iṣẹ àmi, ati iṣẹ iyanu, ati iṣẹ agbara” (2 Kọrinti 12:12).

Paulu waasu fun ọdun kan ati oṣu mẹfa ni Kọrinti. Oluwa ṣiṣẹ pẹlu ọwọ agbara nibẹ, bẹẹ ni ijọ nla si fẹsẹ mulẹ. Nigba ti Paulu kuro nibẹ, eṣu ti mú ọta ti o n pe ara rẹ̀ ni Apọsteli Jesu Kristi yọ́ wọle. O

bẹrẹ si fa awọn eniyan kuro ninu Ihinrere tootọ sẹyin ara rẹ̀. Ki o ba le di olorukọ giga, o tako Paulu o si n bà á jẹ laaarin ijọ. Kò ri ohunkohun wi si iwa Paulu, nitori naa o bẹrẹ si kẹgan irisi ara Paulu ati ọrọ sisọ rẹ̀. Ọta fi idi rẹ̀ mulẹ pe Paulu gbóya ati pe iwe rẹ̀ lagbara nigba ti ko ba si, ṣugbọn nigba ti o ba dé irisi rẹ̀ jẹ alailera ati pe ọrọ rẹ̀ ko ni laari.

Paulu kà wọn si eke Apọsteli, awọn onişẹ ẹtan, ti wọn n pa ra wọn dà di Apọsteli Kristi; o si wi pe ko ya ni lẹnu, nitori ti Satani tikara rẹ̀ n sọ ara rẹ di angẹli imọlẹ, ki yoo si jẹ́ nnkan ajeji bi awọn iranṣẹ rẹ̀ ba n sọ ara wọn di iranṣẹ ododo.

**Fifi Ara Wọn Diwọn Ara Wọn**

Paulu sọ fun wọn pe ki i ṣe iwa ti o mu ọgbọn lọwọ lati maa fi ara wọn diwọn ara wọn. Opin kò si fun bi eniyan ti le ro ara rẹ̀ ga to niwọn igba ti o ṣe pe o n fi ara rẹ̀ wé ara rẹ̀ tabi eniyan ti o rẹlẹ̀ ti ki i ṣe ẹni ti o ga ju u lọ. Paulu pe iwa bayii ni ririn nipa ti ara. “Bi awa tilẹ nrin ni ti ara, ṣugbọn awa kò jagun nipa ti ara: (nitori ohun ija wa ki iṣe ti ara, ṣugbọn o li agbara ninu Ọlọrun lati wó ibi giga palẹ”). O fun wọn ni idaniloju pe oun tun n pada bọ̀ lọdọ wọn ati pe ohun ti oun jẹ́ nigba ti oun kò si ni oun yoo jẹ́ nigba ti oun ba dé.

**Awọn Ẹsun Eke**

Ki a ba le ṣamọna awọn ara Kọrinti wọnyii pada sọdọ Kristi, Paulu mọ pe oun gbọdọ fi awọn ẹri ti o daju wẹ ara oun mọ́. O sọ pe fifunnu lodi si iwa irẹlẹ ti Onigbagbọ, ṣugbọn o gbọdọ jadi awọn iroyin eke ti o ti tankalẹ.

Awọn eke oṣiṣẹ wọnyii n gberaga nipa ti iran wọn. Paulu wá fi idile ti rẹ̀ pẹlu wé ti wọn, o si sọ diẹ ninu ọpọlọpọ nnkan ti oun jiya rẹ̀ nitori Ihinrere. Bi o si ti n mu iṣoro wọnyii wá si iranti, ọkan rẹ̀ lọ sọdọ awọn alailera ti wọn si n jiya, o si wi pe, “Tani iṣe alailera, ti emi kò ṣe alailera? tabi tali a mu kọsẹ̀ ti ara mi kò gbina?” Lẹyin gbogbo idanwo wọnyii o tun ku eyi ti i maa de ba a lojoojumọ: “aniyan gbogbo ijọ.” Oun ki i ṣe ojo. O mura tán lati gbá kiniun mú ni irungbọn ki o si sọ ọ sita. Oun ki yoo jẹ ki ọta yọ́ wọ inu agbo lati wa pa agutan jẹ lai tako o. Paulu le jẹ alailera ninu agọ ara ṣugbọn ki i ṣe ninu ẹmi. O fi gbogbo agbara rẹ̀ ninu ẹmi kọlu ọta alailaanu nì lati bi i wo ki o si gba agutan rẹ̀ silẹ.

**Iṣẹ Awọn Ẹlomiran**

Eke Apọsteli yii ti tẹsẹ bọ agbegbe Paulu ati inu iṣẹ rẹ̀ o si n gbiyanju lati fi wọn ṣe ini bi ẹni pe ti rẹ̀ ni wọn i ṣe. Ẹni yiyẹ kan ni ayé atijọ sọ nipa iru ẹni bẹẹ pe: “O jẹ abuku, ohun irira ati ẹṣẹ patapata fun ẹnikẹni lati ṣe atojubọ sinu iṣẹ awọn ẹlomiran, ati nipa didá rukerudo silẹ laaarin awọn Onigbagbọ, ki o ṣì wọn lọna ki o si ya wọn ni ipá, ki o ba le fa ero sẹyin ara rẹ̀”.

Paulu ko fi igba kan dù lati lọ si ibi ti ẹlomiran ti gbé waasu Ihinrere. O n lọ si awọn ibi ti a kò i ti darukọ Kristi ri, ki o má ba jẹ pe o n mọ amọle lori ipilẹ ẹlomiran.

O tọka si ere ajumọṣe ti a n pe ni Olympic Games o si sọ pe ọyọjuran yii wọ inu ere naa lọna aitọ́. “Ẹniti o ba nṣogo ki o mã ṣogo ninu Oluwa. Nitoripe ki iṣe ẹniti nyin ara rẹ̀ li o yanju, bikoṣe ẹniti Oluwa yin.”

**Iduro Paulu Bi Eniyan**

Awọn ti wọn n fi Paulu sùn sọ pe irisi rẹ̀ jẹ́ alailera, ọrọ rẹ̀ ko si ni laari. Akọwe Griki kan nigba laelae sọ pe Paulu jẹ eniyan kukuru ṣugbọn giga rẹ̀ “kan awọn ọrun.” Wi pe oun ki i ṣe eniyan kan yẹpẹrẹ ṣe e gbagbọ lai ṣe iyemeji, bi bẹẹ kọ oun ki ba ti de ipo ti o wa labẹ olori alufaa ni ṣiṣe inunibini si Ijọ Onigbagbọ́.

Ẹri wà ninu akọsilẹ ti Iṣe Awọn Apọsteli 14:12, nibi ti awọn ara Likaonia fi i pe Herme nitori pe oun ni olori ọrọ isọ fi han pe ọrọ rẹ̀ ni laari. Herme ni ọlọrun olohun iyọ Griki.

**Fifi Agbo-agutan ṣe Ijẹ**

Awọn wolii eke wọnni n rẹ́ agbo agutan jẹ, Paulu si rán awọn ara Kọrinti leti pe lọfẹẹ ni oun waasu Ihinrere fun wọn, oun si n fi ọwọ oun ṣiṣẹ fun aini oun. Nigba ti o ṣe, awọn Ijọ Makedonia si ṣe iranwọ. Ni ẹda ọrọ, o n sọ nipa eyi bi ẹni pe o ti ṣẹ̀ wọn o si n bẹbẹ fun aforiji. O ha ṣe e nitori pe ko fẹran wọn̄

ni? Ọlọrun mọ̀. O fẹran wọn lọpọlọpọ ṣugbọn a fẹran rẹ̀ diẹ kin-un. O ṣogo ninu ominira ti o ni lati waasu Ihinrere ni aidiyele; ati pe ẹnikẹni kò le gba ominira naa lọwọ rẹ̀. O kuku yàn lati maa fi ọwọ rẹ̀ ṣiṣẹ jù lati jẹ́ ẹrù fun ẹnikẹni lọ.

**A Mu u lọ si Ọrun**

Paulu fi hàn gbangba pe oun ko fi kinnkinni rẹyin si olori ninu awọn Apọsteli, o si sọ nipa iriri ti o ni lati ọwọ Oluwa ni ọdun mẹrinla sẹyin. Boya ni gbogbo ọdun wọnyii eyi ti jẹ́ aṣiiri laaarin oun ati Oluwa, ohun ti o ni ọ̀wọ̀ ju lati mẹnukan. Nisisiyii o sọ ọ jade ki oun ba le ran wọn lọwọ lati kuro ninu takute ọta ti wọn ti lù. O sọ pe a mu oun lọ si Paradise ati pe oun ri, bẹẹ ni oun si gbọ́ nnkan wọnni ti ko tọ fun eniyan lati sọ. Awọn iṣipaya wọnyii ga to bẹẹ ti Oluwa ni lati fi ẹ̀gun sii lara lati rẹ̀ ẹ́ silẹ ki o má ba le gberaga kọja aala. O bẹ Oluwa nigba mẹta pe ki O mu un kuro, ṣugbọn Oluwa sọ fun un pe, "Oreọfẹ mi to fun ọ."

Ẹmi Paulu sopọ ṣinṣin mọ ti Jesu Kristi to bẹẹ ti o fi ni ayọ ninu awọn ijiya rẹ̀ nitori Ihinrere. O mọ pe a sọ agbara oun di pipe ninu ailera. Nitori naa ni o ṣe le sọ pe oun ni inu didun ninu ailera gbogbo, ninu ẹgan gbogbo, ninu aini gbogbo, ninu inunibini gbogbo, ninu wahala gbogbo nitori Kristi.

Njẹ nigba ti iyiiriwo ati ipọnju ba wa sọna wa, a ha maa n fi inudidun gbà wọn? Tabi n ṣe ni a maa n sọkun ti a si maa n pohunrere nitori eyi ti o de ba wa? Njẹ wọn maa n mu wa kún fun agbara Ọlọrun ju bẹẹ lọ, tabi n ṣe ni wọn maa n mu itara ati igboya wa lati ja ija rere ti igbagbọ́ dinku? Paulu ti ri aṣiiri nla ti Ihinrere ti o pamọ, kò si si ifẹju Satani kan ti o le ṣi i nipo ni abẹ Apata ti o sá pamọ si.

## AWỌN IBEERE

1 Ki ni ṣe ti Paulu ni lati gbeja jijẹ ti o jẹ́ Apọsteli?
2 Ta ni kọ́ mu Ihinrere tọ awọn ara Kọrinti lọ?
3 Njẹ Satani maa n rán awọn oṣiṣẹ sinu ọgba ajara Oluwa?
4 Ṣe apejuwe irisi wọn.
5 Ki ni a fi fun Paulu lati fi rẹ ẹ silẹ?
6 Ki ni awọn ọta Paulu sọ nipa irisi rẹ̀?
7 Sọ awọn idi ti o fi rò pe wọn parọ.
8 Ọna wo ni Paulu gbà ri owo lati waasu Ihinrere fun awọn ara Kọrinti?
9 Sọ diẹ ninu awọn iyà ti Paulu jẹ nitori Ihinrere.
10 Ninu ki ni Paulu n ṣe inudidùn?'